# ÀLÀYÉ IṢẸ́WÀDÌÍ YÌÍ FÚN ÀWỌN OLÙKÓPA ÀTI ÀWỌN AṢOJÚ WỌN

| | |
|---|---|
| **Àkòrí Iṣẹ́wàdìí** | Aspirin, losartan àti simvastatin lára àwọn agbàwòsàn COVID-19 tí n bẹ ní ilé ìwòsàn: àkànṣe àyẹ̀wò àìṣètòfún kárí-ayé tí kò ní àkọlé (CRASH-19) |
| **Nọmba Ẹ̀dà Awẹ́-ìwé/ Deeti** | ń ọ̀ ìdáhùn 1.0 - deeti 23/04/ 2020 |

## Ìpè láti kópa:

Ilé ìwòsàn yìí ńkópa nínú iṣẹ́ ìwàdìí kárí-ayé kan láti wá ìtọ́jú fún àìsàn COVID-19. A npe àwọn tó ti tó ọmọ ogójì (40) ọdún tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ tí a ti gbà sí ilé ìwòsàn pẹ̀lú àrùn COVID-19, tí a fura sí tàbí tí a fìdí rẹ̀ múlẹ̀, láti dara pọ̀ mọ́ Iṣẹ́ ìwàdìí yìí. Fọ́ọ̀mù yìí n ṣe àlàyé nípa iṣẹ́ ìwàdìí náà títí dórí àwọn àfojúsùn, ewu àti ànfààní kíkópa. Tí o bá fi ara mọ́ ọ láti kópa, a ó sọ pé kí o bu ọwọ́ lu fọ́ọ̀mù ìyọ̀-ǹda kan.

### OHUN TÍ Ó YẸ KÍ O MỌ̀ NÍPA IṢẸ́ ÌWÀDÌÍ YÌÍ:

### 1) Kíni ìdí tí a fi nṣe iṣẹ́ ìwádìí yìí?

Àwọn oníṣègùn rẹ fura, tàbí wọ́n ti fìdí rẹ̀ múlẹ̀, pé o ní àìsàn kan tí a npè ní COVID-19. Èyí ni irú kòkòrò kan tí a npè ní SARS-CoV-2 nfà, tàbí kòkòrò corona, ní kúkúrú. Nnkan bí i méjọ (8) nínú mẹ́wàá (10) nínú àwọn agbàwòsàn tí ó ní kòkòrò corona ni ara wọn ndá láìwá sí ilé ìwòsàn. èyí tí ó pọ̀jù Nínú àwọn tí a gbà sí ilé ìwòsàn ni ara wọn ndá bákan náà, ṣùgbọ́n àwọn kan lè nílò ìtọ́jú tí ó túbọ̀ jinlẹ̀ síi títí dórí gbígba èémí símú tàbí lílo ẹ̀rọ tí ènìyàn fi nmí kí wọ́n tó lè ṣe bẹ́ẹ̀. Síbẹ̀, ara àwọn díẹ̀ kan nínú àwọn wọ̀nyí kìí saàn.

Ní lọ́ọ̀lọ́ọ̀ yìí, kò sí oògùn kankan fún ìtọ́jú COVID-19 bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ètò ńlọ lórí ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ rẹ̀ lọ́wọ́. A nṣe iṣẹ́ ìwàdìí yìí láti mọ̀ bóyá nípa ṣíṣe àwọn àlékún ìtọ́jú láti ṣe àtìlẹ́yìn fún ọkàn àti àwọn ẹ̀dọ̀fóró nígbà tí ara àwọn agbàwòsàn kò bá yá, a lè mú kí bí ó ṣe nṣe wọn gbé pẹ́ẹ̀lí sí i.

### 2) Kínni èrèdí iṣẹ́ ìwàdìí yìí?

Àfojúsùn iṣẹ́wàdìí yìí ni láti ṣe àfiwé oríṣi ìtọ́jú mẹ́ta tí a mọ̀ pé ó máa nṣerànwọ́ fún àwọn tí ó ní ìṣòro ti ọkàn àti ti èémí, èyítí ó sì lè wúlò fún àwọn agbàwòsàn tó ní COVID-19. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ìtọ́jú yìí wúni lórí, kò sí ẹni tí ó mọ̀ bóyá èyíkéyìí nínú méjèèjì yóò wúlò ní ṣíṣe ìrànlọ́wọ́ fún àwọn agbàwòsàn láti ní ìmúláradá ju òdiwọ̀n ìtọ́jú àtẹ̀yìnwá ní ilé ìwòsàn rẹ (èyí tí gbogbo ènìyàn yóò gbà).

Àwọn ìtọ́jú tí a lè fún ọ, ní àfikún sí ìtọ́jú ti àtẹ̀yìnwá ní ilé ìwòsàn rẹ, ni:

- Aspirin (tí a sáábà máa nló láti dènà àìsàn ọkàn ṣíwọ́-iṣẹ́ àti rọ-lápá rọ-lẹ́sẹ̀)
- Losartan (tí a sáábà máa nló láti tọ́jú ìfúnpá gíga, dáàbò bo kindinrín àti ṣe àdínkù sí ìnira ọkàn)
- Simvastatin (tí a sáábà máa nló láti mú kọlẹ́stẹrọọl wálẹ̀)
- Àpapọ aspirin àti/tàbí losartan àti/tàbí simvastatin
- Ojúlówó ìtọ̀jú láìsí àfikún ìtọ̀jú míràn

### 3) Tani ó ń ṣe iṣẹ́ ìwàdìí yìí?

Ikọ̀ àwọn olùwádìí láti London School of Hygiene and Tropical Medicine (University of London) ní United Kingdom (Ìlú Ọba) ni ó nṣe iṣẹ́wàdìí yìí. Àwọn oníṣègùn àti nọ́ọ̀sì ní àwọn ilé ìwòsàn káàkiri àgbáyé ńkópa bákan náà.

### 4) Àwọn wo ni iṣẹ́ ìwàdìí yìí kàn?

A lè fi àwọn agbàwòsàn sára iṣẹ́wàdìí yìí tí wọ́n bá ti pé ọmọ ogójì (40) ọdún ó kéré tán, tí oníṣègùn sì nfura tàbí ti fi ìdí àìsàn COVID-19 múlẹ̀. A kò ní ì fi àwọn agbàwòsàn tí oníṣègùn náà bá lérò pé èrèdí kan wà ní pàtó tí àwọn ìtọ́jú iṣẹ́ ìwàdìí náà kò fi bójú mu si ara wọn, fún bí àpẹẹrẹ, tí a ti mọ̀ pé ọ̀kan lára wọn lè gbòdì lọ lára rẹ. Àwọn agbàwòsàn tí nfi èrọ mí tẹ́lẹ̀tẹ́lẹ̀ kò lè kópa bákan náà. Nnkan bí ẹgbẹ̀rún mẹ́wàá (10,000) agbàwòsàn ni yóò máa kópa nínú iṣẹ́ ìwàdìí yìí kárí ayé. Ó kù sí ọ lọ́wọ́ láti pinnu bóyá o fẹ́ kópa tàbí bẹ́ẹ̀kọ́.

### 5) Kínni yíò ṣẹlẹ̀ lẹ́yìn tí mo bá yọ̀-ǹda láti kópa nínú iṣẹ́ ìwàdìíyìí?

Tí o bá pinnu láti dara pọ̀, a ó sọ pé kí o bu ọwọ́ lu fọọmu ìyọ̀-ǹda. A ó wá tẹ àlàyé ṣókí nípa ipò ìlera àti ti ìtọ́jú-ìṣègùn rẹ sínú ẹrọ ayára-bí-àṣá kan. Ẹ̀rọ ayára-bí-àṣá náà yóò wá pinnu èyí-jẹ-èyí-ò-jẹ àwọn ìsọ̀rí yoowu ìtọ́jú tí o bọ́ sí. Ní gbogbo ọ̀nà, irú ìtọ́jú tí ilé ìwòsàn rẹ ti maa n fún irú agbàwòsàn bíì rẹ tẹ́lẹ̀ naa yoo wà nínu rẹ̀. Ó tún lè ní àfikún ìtọ́jú kann nínú, eyití a ó fún ọ láti ẹnu tàbí tí o bá nṣàìsàn púpọ̀, tí yoo jẹ́ nípa àtẹ̀bọ̀ nínú ikùn rẹ tí ounjẹ yoo maa gba wọle. Ìwọ tàbí àwọn oníṣègùn rẹ kò lè yàn èyí tí a ó fún ọ nínú àwọn ìtọ́jú náà. Tí wọ́n bá ti yan ọ̀kan, méjì tàbí méta fún ọ nínú àwọn ìtọ́jú náà, ìwọ yóò gbà wọ́n ní ọ̀kọ̀ọ̀kan lójúmọ́ fún ó pọjù ọjọ́ méjìdínlọ́gbọ̀n tàbí títí di ìgbà tí a ó dá ọ sílẹ̀ ní ilé ìwòsàn èyíkéyìí tí ó bá kọ́kọ́ wáyé. A ó ṣe àkọsílẹ̀ àfikún àlàyé nípa ìlera rẹ a ó sì tẹ̀ ẹ́ sínú ẹ̀rọ ayára-bí-àṣá kan ṣùgbọ́n a kò níí eṣ àfikún ìbẹ̀wò lẹ́yìn tí o bá ti kúrò ní ilé ìwòsàn.

### 6) Kínni àwọn ànfààní tí ó lè jẹyọ ní kíkópa nínú iṣẹ́ ìwàdìí yìí?

A kò mọ̀ bóyá èyíkéyìí nínú àwọn ìtọ́jú tí a ndán wò yóò ní àfikún ànfààní. Iṣẹ́ ìwàdìí ìtọ́jú rẹ lè ṣe ọ ní anfaani tàbí kí ó má ṣe iwọ fúnrarẹ ní anfaani yoowu, ṣùgbọ́n iṣẹ́ ìwàdìí yìí yoo ṣe anfaani fún àwọn agbàwòsàn lọjọ́ iwájú.

### 7) Kínni àwọn ewu tí ó lè jẹyọ ní kíkópa nínú iṣẹ́ ìwàdìí yìí?

Yàtọ̀ sí àwọn ohun tí a ti mọ̀ pé ó lè jẹyọ látàrí àwọn ìtọ́jú yìí (lára èyí tí a ti lè rí inú kíkún, ẹ̀jẹ̀ yíya àti òòyì ojú tí kò wọ́pọ̀), kò fi bẹ́ẹ̀ ṣeéṣe kí oògùn iṣẹ́ ìwàdìí kan gbòdì lọ lára. Jọ̀wọ́ béèrè lọ́wọ́ oníṣègùn ilé ìwòsàn rẹ tí ìwọ yóò bá fẹ́ àfikún àlàyé. Ní kété tí a bá ti kà ọ́ mọ́ iṣẹ́ ìwàdìí yìí, ìwọ àti oníṣègùn rẹ yóò mọ̀ ìtọ́jú tí ayára-bí-àṣá yàn fún ọ. Lílo àwọn oògùn iṣẹ́ ìwàdìí yìí kìí ṣe àjèjì sí àwọn oníṣègùn rẹ wọn yóò sì mọ̀ bóyá ohunkóhun lè jẹyọ tí wọ́n lè wọ̀nà fún.

## 8) Njẹ́ mo lè fi òpin sí ìtọ́jú iṣẹ́ ìwàdìí náà tàbí íkópa mi ṣáájú àkókò?

Bẹ́ẹ̀ni. Tí ìwọ tàbí onísègùn rẹ bá fẹ́ fi òpin sí ìtọ́jú rẹ nígbàkúùgbà, ẹ wà ní òmìnira láti ṣe bẹ́ẹ̀. Tí o bá pinnu pé o kò fẹ́ kí wọ́n gba ìfitónilétí yòówù nípa rẹ mọ́, o wà ní òmìnira láti sọ bẹ́ẹ̀ (bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ikọ̀ olùwádìí yóò máa ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn àlàyé tí a ti gbà títí dé ìkóríta yẹn).

## 9) Tí mo ba ní ìbéèrè tàbí ìṣòro yòówù, tani mo lè kàn sí?

Tí o bá ní ìbéèrè tàbí ìṣòro yòówù jọ̀wọ́ bá ikọ̀ ìṣègùn ilé ìwòsàn rẹ sọ̀rọ̀. Àfikún àlàyé nípa Iṣẹ́ ìwàdìí náà tún wà ní àrọ́wọ́tó lójú òpó ti Iṣẹ́ ìwàdìí yìí (http://crash19.lshtm.ac.uk/).

## 10) Àkọsílẹ̀ wo ni ẹ nṣe ní ọ̀rọ̀ àṣírí?

Gbogbo àkọsílẹ̀ nípa rẹ àti ìlera rẹ ni a ó ṣe ní ọ̀rọ̀ àṣírí. Àwọn ènìyàn tí a gbà láàyè láti wo àkọsílẹ̀ náà nìkan ni yóò jẹ́ àwọn onísègùn tí ó nṣe Iṣẹ́ ìwàdìí náà, àwọn òṣìṣẹ́ ní ojúkò àbójútó Iṣẹ́ ìwàdìí láti London School of Hygiene and Tropical Medicine (University of London), àti àwọn aláṣẹ tí ó nbójútó pé kí wọ́n ṣe Iṣẹ́ ìwàdìí náà dáradára. Àwọn ilé ìwòsan kan lè má lè ṣe àfipamọ́ ẹ̀dà fọọmu ìyọ̀-ǹda oní beba kan nítorí ewu ìtànkálẹ̀ kòkòrò corona. Tí ó bá rí báyìí ẹ̀dà fọọmu ìyọ̀-ǹda náà tí yóò ní orúkọ àti ìbọwọ́lù rẹ lára rè ni a ó fi pamọ́ sórí ẹ̀rọ ní ojúkò àbójútó Iṣẹ́ ìwàdìí náà ní ìlú London. A ó fi ọwọ́ àṣírí múu a kò sì níí fi ṣọwọ́ sí ọ̀dọ̀ ẹlòmíràn yòówù. A kò níí lo orúkọ rẹ nígbà tí a bá tẹ àwọn èsì náà jáde. Àfiyèsí ọ̀rọ̀ àṣírí wà ní ojú òpó iṣẹ́ ìwàdìí yìí.

## 11) Njẹ́ dandan ní kí n kópa?

Ó kù sọ́wọ́ rẹ láti pinnu láti dara pọ̀ mọ́ iṣẹ́ ìwàdìí yìí , dídara pọ̀ jẹ́ ti ẹni tí ó bá wù. Ìpinnu rẹ láti kópa tàbí láti máṣe kópa kò níí ní ipa lórí ìtọ́jú tí o ngbà ní ilé ìwòsàn yìí.

## 12) Ṣé ìdíyelé tàbí owó sísan kankan wà?

Ọ̀fẹ́ ni ìtọ́jú iṣẹ́ ìwàdìí yìí . A kò níí sanwó fún ìwọ tàbí àwọn òṣìṣẹ́ ìṣègùn rẹ fún kíkópa yín nínú iṣẹ́ ìwàdìí yìí.

## 13) Kínni ó tún kù tí ẹ tún lè sọ fún mi?

London School of Hygiene and Tropical Medicine ni ó kówó lé iṣẹ́ ìwàdìí yìí, kìí ṣe àwọn tí ó ṣe èyíkéyìí nínú àwọn oògùn iṣẹ́ ìwàdìí yìí. Tí a bá rí ìfitónilétí tuntun tí ó lè ní ipa lórí ìpinnu rẹ láti dúró sínú iṣẹ́ ìwàdìí náà, a ó fií fún ọ. Tí ohunkóhun bá bá ọ̀nà míràn yọ tí ewu sì wu ọ́ ní àkókò iṣẹ́ ìwàdìí yìí, London School of Hygiene & Tropical Medicine ni yóò ṣe agbáterù fún ẹ̀tọ́ fún ewu yòówù tí kìí se èyí tí àìkàsí fà. Láti bójútó èyí tí ó jẹ mọ́ ọ, ìsọ̀rí àwọn ènìyàn kan tí kìí ṣègbè tí a pè ní Research Ethics Committee [National Health Research Ethics Committee] ti yẹ ẹ́ wò. Wọ́n fi ara mọ́ ọ pé ó dára fún wa láti ṣe iṣẹ́ ìwàdìí yìí.

Iṣẹ́ ìwàdìí yìí tún gba àṣe láti le è di ṣíṣe ní Nigeria láti ọwọ́ọ

The Director, Drug Evaluation & Research Directorate
National Agency for Food and Drug Administration and Control (NAFDAC)
Address: Oshodi Apapa Expressway, Oshodi, Lagos
Tel: + 234-435555333

Àbájáde ìkẹyìn iṣẹ́ ìwàdìí yìí yóò wà ní àrọ́wọ́tó ní ojú òpó ní kété tí a bá ti tẹ̀ ẹ́ jáde.

CRASH-19

# FỌỌMU ÌYỌ̀-ǸDA OLÙKÓPA

**Àkòrí Iṣẹ́ ìwàdìí:** Aspirin, losartan àti simvastatin lára àwọn agbàwòsàn COVID-19 tí ó wà ní ilé ìwòsàn: àkànṣe àyẹ̀wò àìròtẹ́lẹ̀ kárí-ayé tí kò ní àkọlé (CRASH-19)

| | |
|---|---|
| **Orúkọ Ilé Ìwòsàn:** (lo ÀWỌN LẸTA NLÁ) | |
| **Orúkọ Olùkópa:** (lo ÀWỌN LẸTA NLÁ) | |
| **Nọmba ninu Ẹ̀rọ Ayára-bí-àṣáAyára-bí-àṣá :** (tẹ nọmba ninu ẹ̀rọ ayára-bí-àṣáayára-bí-àṣá naa) | |

**1. A ti pèsè àlàyé nípa iṣẹ́ ìwàdìí yìí fún mi:** Mo fi ìdí rẹ̀ mùlẹ̀ pé mo ti kà (àbí a ti kà á sí mi létí) mo sì lóye àkóónú Awẹ-iwé Àlàyé nípa Olùkópa náà (nọmba ẹ̀dà àti 1.0, deeti 23/04/2020) mo sì ti ní ànfàànì láti gbé àlàyé náà yẹ̀wò tí mo sì ti béèrè àwọn ìbéèrè. Wọ́n ti fèsì tó tẹmilọrun sí ìwọ̀nyí.

**2. Kíkópa tí kì í ṣe Tipátipá:** Ó yé mi pé ìkópa kì í ṣe tipátipá àti pé mo ní òmìnira láti yọwọ́ nígbàkúùgbà, láìsọ èrèdí kankan, láìsì ní ipa lórí ìtọ́jú ìṣègùn tàbí àwọn ẹ̀tọ́ mi lábẹ́ òfin.

**3. Mo yọ̀-ǹda àkọsílẹ̀ nípa mi:** Mo yọ̀-ǹda kí awọn tí a fún ní àṣẹ láti ilé ìwòsàn yìí, London School of Hygiene and Tropical Medicine àti àwọn aláṣẹ olùtọ́sọ́nà ní anfaani lati lè wò àwọn abala tí ó yẹ nínú àwọn akọsilẹ ìtọjú àti ìfitónilétí nipa mi, ní bòńkẹ́lẹ́, lati rí i daju pé wọ́n nṣe iṣẹ́ ìwàdìí yìí bí ó ti yẹ.

**4. Mo yọ̀-ǹda àkọsílẹ̀ nipa itọju-ilera mi:** Mo fi ara mọ́ ọ pé kí a fi àlàyé nipa itọju-ilera láìsí àlàye ti ara mi) tí àwọn oníṣègùn àti nọọsi ní àwọn ilé ìwòsàn tí ó npèsè ìtọ́jú fún mi ti gbà ránṣẹ́ sí London School of Hygiene & Tropical Medicine. Mo fi ara mọ́ ọ bákan náà pé kí a ṣe alábàápín ìfitónilétí yìí tí kò lè júwe mi ní ọ̀nàkọ́nà pẹ̀lú àwọn oníṣẹ́ ìwàdìí míràn ní ojú àtẹ ará ìlú.

**5. Àkọsílẹ̀ tí a fi pamọ́ sínú ẹ̀rọ ayára-bí-àṣáayára-bí-àṣá:** Ó yé mi pé a ó tún fi ìfitónilétí nípa ìtẹ̀síwájú mi pamọ́ sí ojú àtẹ kan, àti pé a ó fi àkọsílẹ̀ yìí pamọ́ sórí àwọn ẹ̀rọ ayára-bí-àṣá tí London School of Hygiene and Tropical Medicine ndarí. Ó yé mi pé a ó pa àkọsílẹ̀ yìí mọ́ láìsí ewu àti ní ìdákọ́nkọ́.

**6. Lílò fọọmu ìyọ̀-ǹda yìí:** Mo fi ààyè sílẹ̀ pé kí ẹ̀dà orí ẹ̀rọ ti fọọmu ìyọ̀-ǹda yìí, tí ó ní orúkọ mi, wà ní àrọ́wọ́tó fún London School of Hygiene & Tropical Medicine tí ó ba yẹ láti ṣe bẹ́ẹ̀.

**7. Gbígbà láti kópa:** Mo gbà láti kópa nínú iṣẹ́ ìwàdìí òkè yìí.

| | | |
|---|---|---|
| ................................................. | ........................................ | ......../......../........... |
| Orúkọ olùkópa (Lo ÀWỌN LẸTA NLÁ) | Ìbuwọ́lú/Ìka títẹ̀ tàbí àmì míràn (tí kò bá lè bu ọwọ́ lu ìwé) | Deeti òní |
| ................................................. | ........................................ | ......../......../........... |
| Orúkọ ẹni tí ó gba ìyọ̀-ǹda (Lo ÀWỌN LẸTA NLÁ) | Ìbuwọ́lù | Deeti òní |

**Tí olùkópa kò bá lè kà ohun tí a kọ àti/tàbí bu ọwọ́ lù ú fúnra wọn ṣùgbọ́n tí wọ́n ní agbára láti fi ara mọ́ ọ:**

Mo ṣe ẹlẹ́rìí pé wọn ka fọọmu ìyọ̀-ǹda yìí sí ẹni tí ó fẹ kópa náà leti dáadáa, bí ẹni tí ó lè béèrè ìbéèrè tí ó sì lè gba èsì tí ó tẹ ẹ lọrun gbà. Mo fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé wọn fi ara mọ́ ọ láìsí tipátipá.

| | | |
|---|---|---|
| ................................................. | ........................................ | ......../......../........... |
| Orúkọ Ẹlẹ́rìí (Lo ÀWỌN LẸTA NLÁ) | Ìbuwọ́lù | Deeti òní |

**Ẹ̀dà kan fún olùkópa; Ẹ̀dà kan tí a ó fi pamọ́ sínú àwọn àfiyèsí ìṣègùn; Ojúlówó fún faili ojú òpó Olùwádìí. Tí ewu nlá bá wà pé àìsàn lè ràn láti ara ìfipamọ́ fọọmu ìyọ̀-ǹda, a ó fi ẹ̀dà ti orí ẹ̀rọ ránṣẹ́ sí LSHTM; ẹ̀dà fún olùkópa*

The NHREC assigned number is: NHREC/01/01/2007

Approval dates: 21/05/2020to 20/05/2021.

# FỌỌMU ÌYỌ̀-ǸDA AṢOJÚ-ẸNI

**Àkòrí Iṣẹ́ ìwàdìí:** Aspirin, losartan àti simvastatin lára àwọn agbàwòsàn COVID-19 tí ó wà ní ilé ìwòsàn: àkànṣe àyẹ̀wò àìròtẹ́lẹ̀ kárí-ayé tí kò ní àkọlé (CRASH-19)

| | |
|---|---|
| **Orúkọ Ilé Ìwòsàn:** (lo ÀWỌN LẸTA NLÁ) | |
| **Orúkọ Olùkópa:** (lo ÀWỌN LẸTA NLÁ) | |
| **Nọmba ninu Ẹ̀rọ Ayára-bí-àṣáAyára-bí-àṣá :** (tẹ nọmba ẹ̀rọ ayára-bí-àṣáayára-bí-àṣá naa) | |

**Ti olùkópa kò bá ní agbára láti sọ pé òun fi ara mọ́ ọ fún sáà díẹ̀ nítorí ipò ìlera rẹ̀ to le (fún àpẹẹrẹ èémí tí kò já gaara rárá, àìbalẹ̀-ọkàn tàbí nínílò afẹ́fẹ́):**

- Mo ti ka ìfitónilétí yii (tàbí wọn ti kà á sí mi létí) mo sì ní ànfààní láti béèrè àwọn ìbéèrè.
- Ó yé mi pé wọn maa béèrè pé kí olùkópa fi ìdí ìyọ̀-ǹda rẹ̀ múlẹ̀ ní kété tí ó bá ti ní agbára láti ṣe bẹ́ẹ̀ àti pé tí ó bá fẹ́, ó lè yọwọ́ kúrò nínú iṣẹ́ ìwàdìí yìí láìjẹ́ pé ó ṣe àkóbá kan fún ìtọ́jú ílera rẹ̀.
- Mo gbàgbọ́ pé tí ó bá lè ṣe bẹ́ẹ̀, olùkópa náà yóò fi ara mọ́ ọ láti kópa nínú iṣẹ́ ìwàdìí yìí.

| | | |
|---|---|---|
| ………………………………………… | ………………………………… | ……../……../………… |
| Orúkọ Aṣojú-ẹni (Lo ÀWỌN LẸTA NLÁ) | Ìbuwọ́lú/Ìka títẹ̀ tàbí àmì míràn (tí kò bá lè bu ọwọ́ lu ìwé) | Deeti òní |

…………………………………………
Ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú olùkópa

| | | |
|---|---|---|
| ………………………………………… | ………………………………… | ……../……../………… |
| Orúkọ ẹni tí ó gba ìyọ̀-ǹda (Lo ÀWỌN LẸTA NLÁ) | Ìbuwọ́lù | Deeti òni |

**Ẹ̀dà kan fún Aṣojú; Ẹ̀dà kan tí a ó fi pamọ́ sínú àwọn àkọsílẹ̀ iṣẹ́-ìtọ́jú; Ojúlówó fún faili ori ibùdó-ayélujára Olùwádìí. Tí ewu nlá bá maa wà pé àìsàn lè ràn ẹlomiran lati ara afipamọ́ fọọmu ìyọ̀-ǹda, a ó fi ẹ̀dà ti orí ẹ̀rọ ránṣẹ́ sí LSHTM; ẹ̀dà fún Aṣojú-ẹni*